# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. IV. No. 176 SATURDAY, NOVEMBER 28, 1925. 4d.

***The People's Leading Vernacular Paper.***

**N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.**
**OYINBO *J. F. SICK***

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko

A jẹ Ajirera ninu ọwọ Ilẹkẹ, orişirisi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita —

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹke Olomi Waji, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwọrọ ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jọjọ, Ilẹkẹ Olokuta, Ilẹke Oloruka, Ilẹkẹ Elẹranko, Ilẹkẹ Didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ileke Mọjọkun, Ileke Adumădan

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọnyi fun tita :—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aṣọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aṣọ Iṣ'ọṣọ, Ẹro Ere Ọmọde, Ohun Ọṣọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbẹje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi ọwọ wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni:— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

---

***Electric Novelties.***

Mr. M. SADIKU has assorted kinds of Electric Materials, 2 & 3 lights, Brackets, Shades, etc, too numerous to mention.

He undertakes the contract of wiring houses at very reasonable prices.

And has also in stock louder bells complete with wire and Salamonical ready for connections. Call at 18 Ọbun Eko Street, Lagos, for your selection.

*P.O. Box 378.*

---

**WHO SAYS TOOLS?**

Ọgbẹni J. O. BANKỌLE ti Daddy Alaja *Street, Lagos*, ni wabiwọsi irin iṣẹ *Carbenter*, fun tita, awọn irinṣẹ bi Kọkọrọ, *Rachel Braces, Coffin Handles, Wall Papers*, ati bẹbẹ lọ. Ọpọku ọyọku ni owo wọn. Jọjọ nyaju ni wọn.

# OPEN AGAIN

## AND IN

# FULL SWING

# LEVER

# STORE

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## WEEKLY TALKS
BY
## *"The Service Company."*

### ILLUSIONS.

Most people—all practical people—as Barry Pain says, would not willingly be the victims of an illusion. Illusions they say, quite rightly, are unreal and deceptive.

Illusions, because they are completely deceptive whilst they last, are just as good as reality. The only rational objection to pleasant illusions is that the existence is brief and precarious. If only your illusions would last your lifetime you would be more than content, it is only when your illusions cease that you feel the pain.

From all of which it follows that illusions whilst they last bring the greatest contentment and happiness. An now translate these illusions to terms of everyday material significance. If you eat an apple and enjoy it you do not curse it because it is no longer there. You may even say with satisfaction "that was quite a good apple." If at some period you have had any article at all which during its period of existence, brief or otherwise, has given you satisfaction, has been a pleasure to you, has however subtly given you the pleasant illusion that your "possesion" expresses your individuality and belongs to yourself alone, then it obviously does not follow that this sense of satisfaction is an illusion. It is a reality. And there is no source from which these pleasant illusions which materialise so readily, into even more pleasant realities, can be obtained more efficiently than from THE SERVICE COMPANY of Broad Street, Lagos. The Service Company will give you a "Lotus" and "Delta" Shoe which in itself is a poem in shoes; they will also guide you in the selection of a shirt, advise you on the Scheme of your attire to the smallest detail. The same with every other article you may require The Service Company will get it for you; the quality and the satisfaction it will give you will be no illusion but a thing of beauty and a joy for ever.

Come and see us.

THE SERVICE COMPANY.
Broad Street *( Near Tinubu Street )*
Lagos.

## *GBOHUN-GBOHUN.*

### Ẹ KU 'RIN.

Gomina Agba Sir Græme Thomson lọ bẹ Ibudo awọn Ọlọpa l'Ebute Mẹta ati ni Ita Tinubu wo ni *Tuesday* ọsẹ yi; kete ti awọn to gbọ pe Gomina wa bẹ Ibudo awọn Ọlọpa wo ni Ita Tinubu, ibọ di ẹsẹ ko gbeji.

### RẸ RẸ O, ONIYAWO A-DE O.

Iya-afin Phebe Johnson ati Ọgbẹni S. A. Ṣogbẹsan yio gbe iyekan wọn, Omidan Felicia Ayọdele niyawo fun Alufa Theodosius Oluwọle Dedẹkẹ, oloye B.A. ni Ṣọṣi Jude Apọstili Mimọ l'Ebute Mẹta ni ọjọ kẹwa oṣu *December* t'o mbọ.

### O TO GBE, ẸLẸRU GBE.

A gbọ pe Gomina Agba npete ati lọ si Kano ni *Tuesday* ọsẹ ti a o bọ si; akọkọ lọ soju irin ti Gomina Agba yio kọ lọ leyi lati igbati o ti de silẹyi.

### IRẸSI MI JOJO!!!

Ọpa alaiye ti a gbọ lọsẹ yi nipasẹ ti Jile ni ẹgbẹdogun Apo Irẹsi bọlibọli ti a sọpe nwọn pọra ni Ile-ẹrù *( Stores )* awọn Oyinbo *Miller* l'Ẹhingbẹti gọ́ ẹnikẹni.

Awọn gbajumọ diẹ ni a si sọpe awọn Ọpa Ọba ti da duro nipa ọran na. Ki Baba ṣọ ni.

### ABỌ O.

A ki Ọgbẹni wa E. Olu: Bright kabọ ọna Kano, Jos, Ile Ifẹ ati Ode Ondo ti o ti gba isinmi lọ ni lile loṣu kan sẹhin. Ọgbẹni Bright de ni *Wednesday* ọsẹ yi, cju rẹ si tutu pẹsẹpẹsẹ bi oju ọkọ iyawo; dajudaju atẹgun itura ọna Ilu Oke lo njẹ bẹ. Abọ o!

## "EKO AKETE" LAW REPORT.

[ Lati ọwọ ATOLUGBOKUN. ]

Anu ṣe mi pupọ fun nyin to ngbadun irohin ile-ẹjọ ti mo nkọ ni ọsọsẹ wipe mi o le rohin fun nyin lati bi ọsẹ diẹ sẹhin nitoripe ailera mi ni ko jẹ, mo si dupẹ lọwọ Ọlọrun pe mo nri alafia. Irohin ti mo fẹ fun yin ni ọsẹ yi ohun ni pe ikan ninu awọn to nfun mi ni iro gbọ ni Eko ati ni ilu miran fi labari ṣowọ si mi nipa irin ajo wọn ni ọna Warri, Aba ati Portharcourt nipa ẹjọ ganran *( Assizes holden at Easten Divisions )* eyi ti wọn ṣe ni ọhun gẹgẹ bi labari na ti ṣe de ọwọ mi ni mo ma sọfun yin ati irin ajo wọn ni ati ilu oke nibiyi titi won fi de Warri. Ni agogo meji-abọ ni ọsan ijọ *Thursday* ijọ kọkandilọgbọn oṣu *October* 1925. *( Thursday the 29th day of October* 1925 *) Motor Car L* 1350 ati *L* 950 kuro ni igboro Eko awọn ẹniti o wa ninu *L* 1350 ni Lọya Adekun'e Wright ati Montacute Thompson, pẹlu akọwe Lọya Wright Ọgbẹni N. O. Macauley *( Typist )* awọn to wa ni *L* 950 ni Ọgbẹni J. Adolphus Bright ati awọn ọmọde mẹta wọn mu ọna Ibadan pọn, nigbati won de 93¼ *miles Motor L* 950 taku wọnle ko ṣisẹ mọ, nigbati awa *Motor* Abiọdun wo *Motor* yi, o ni arun kan nba gẹnẹretọ wi, wọn wa nibẹ titi di agogo mẹjọ-abọ iṣẹ aje sa nipa ibẹ ni awọn Lọya mejeji gbe ko ẹru inu *Motor* ti wọn dalẹ wọn gbera o di Ibadan won la pe ẹniti o ma tun ṣe wa, ibiti a wi yi o to *miles* 26¾ si Ibadan wọn lọ wọn pada de ni agogo mọkanla oru, ẹniti o ma tun ṣe orukọ rẹ njẹ Samson (ki ṣe Samisin alagbara re kọja) wọn si wa nibẹ titi di nkan agogo mejila nigbati ko ṣeṣe, awọn Lọya yi ni ki wọn ko gbogbo ẹru inu *L* 950 si *L* 1350 wọn si yọ ọmọde meji silẹ nibẹ pẹlu *Driver* Lasisi ẹniti o nmu 1350 lọ wọn si ni ki *Driver* Abiọdun ko bọ si 1350 gbogbo wọn gbera wọn nlọ si Ibadan nigbati wọn de 107 *miles* ẹsẹ *Motor* 1350 kan bẹ. wọn tun duro wọnle, wọn tun pada sẹhin boya wọn atitun 950 ṣe nigbati wọn 93¼ *miles* wọn tun ṣe diẹ, ẹniti o tun ṣe ni on arun 950 de Ibadan ki on la pari rẹ ibẹ ni 1350 ati 950 gbera o tun di Ibadan wọn de Ibadan ni agogo mẹta arọ ko si orun kan mọ, nigbati o di dede agogo mẹsan arọ ti ko si mọsan kan ni ara 950 ibẹ ni Lọya Wright gbe gbera o di Ṣabu John Holt ni Ibadan ọ lọ ra rọba mẹrin titun fun 1350. *(4 Inner Tubes)* ibẹ ni wọn wa ko da si ẹsẹ 1350. Lẹhinna Ọgbẹni Dan Donald Quist gbe pe awọn Lọya wọnyi ati akọwe Agba ati Kekere fun awowo omi gbigbona ati ata to gba muṣe. Wọn fi Ibadan silẹ ni agogo mẹwa arọ ijọ *Friday* o di Ile Ifẹ 56 *miles* pẹlu 1350 wọn fi 950 silẹ pẹlu *Driver* Lasisi ati awọn ọmọde meji *Driver* Abiọdun ẹniti ọna daloju daradara lo bọ si 1350. Wọn kọja ni Ile Ifẹ bi iṣẹju o di Ilesha 20 *miles* wara were wọn de bẹ wọn ra *Petrol* wọn ko sinu *Motor* wọn gbera o di Igbara Oke 32 *miles* ni ọna Ilesha si Igbara Oke ẹru ọmọ ọjẹjẹ nibẹ ẹniti o ba joko wipe mo nwa *Motor* ni Ita Tinubu lọ si Ebute Mẹta ko wa la dan ibẹ wo, oyi akọ loju ; ọga ni *Driver* Abiọdun ẹniti oyi ibẹ da loju rẹ were o ti kọja o di Akurẹ 41¼ *miles* wọn kọja ni Akurẹ won ya ọna Ondọ silẹ o di Ọwọ 34 *miles* ki wọn to de Ọwọ ojo diẹ fẹrẹ pa wọn fun iwọn 6 *miles* wọn kọja ni Ọwọ. wọn gbera o di Ifọn 17 *miles* wọn kọja ni Ifọn Ibẹ ni ojo taratara gbe pa wọn ninu *Motor* gbogbo wọn di arọ sinu *Motor* wọn tutu jn ẹja ojiji lọ, ọna ibẹ bajẹ pupọ irọfọ ni *Motor* ko le rin ju 10 to 15 *miles speed* lọ, awọn Afara kekeke ati nla jẹ mẹrindilogun gbogbo rẹ ti di ọkẹjẹ Ifọn si Benin City 53 *miles* wọn de Benin City won rọra kọja ni *Lagos Street* ẹniti o ba kọja ni ita Eko yi, yo niran Eko, a de bẹ agogo mẹjọ-abọ ni alẹ a kọja o di Sapẹlẹ 32 *miles* a de Ebute Sapẹlẹ ni agogo mẹwa awọn ti wọn fi ọkọ gbe *Motor* sọda si o di keji ti ṣiwọ wọn ni lati sun ni Ebute Sapẹlẹ titi di arọ, gbogbo won kako ẹfon ni on ẹfon wọn jẹ ọmọ enia titi inu bọsẹ towọ si ẹsẹ, wọn fi ara da titi ilẹ mọ nigbati o di agogo meji arọ oko de to ma gbe *Motor* sọda, ọkọ yi de pẹlu Ibitayọ Olowu ikan ninu ọmọ Ologbe Olowu Idunmagbo nibi ẹniti o jẹ pe on lo lọ ji awọn ọlọkọ lati tete gbe *Reo Lorry* ti rẹ kọja nigbati o si ri awọn ọmọluwabi to wa ninu *L* 1350 o ni ki awọn ọlọkọ gbe 1350 kọja na, on na si ba wa pada on lo ba wa gba iwe aṣẹ *( pass )* lati wa *Motor* lọ si Warri ni ofisi Ajẹlẹ *( DO's office )* a kuro ni Sapẹle ni agogo mẹsan kọja iṣẹju mẹdogun o di Warri 28 *miles* a de Warri si agogo mẹwa arọ ijọ *Saturday* 31/10/25.

Lọya Percy Wallwin Holm ẹniti Lọya Wright ti ranṣẹ si pe on nbọ si gba tọwọ tẹsẹ. Lọya Thompson si wọ sile rẹ ti o ma de si, gẹgẹ bi ile Lọya Holm ko ti gba ye to lati gba awọn Akọwe meji sile tirẹ, lẹsẹkẹsẹ o ti sọ wọn lọjọ si ile Iyalode Okere Iya afin ti orukọ re njẹ Leleji wara were Iya afin yi ti gba Ọgbẹni Bright ati Akọwe rẹ sọwọ sẹsẹ, ile yi ko ju iṣẹju meji si ti Lọya Holm. Nigbati o simi tan Lọya Holm, Wright ati Bright Lọya Holm mu wa lọ si *Magistrate Court* ati Ọfisi Waya Nibiti awọn Bright gbe de si, ibẹ ni wọn ṣi Ofisi. Awọn Lọya ti wọn ba ni Warri ni. Bucknor, Holm, Ata-Amonu, Asifo Ẹgbẹ, Ọbafẹmi, Pyne, Shyngle ati Crown Counsel Oyin o Ọgbẹni Fitz Gerald awọn Lọya wọn yi ti de ṣiwaju wa lọjọ to ti pẹ. Ni oju alẹ Ọgbẹni Bright gba atẹgun lọ si ọja wọn ti nwọn npe ni *(Ogbe Ijoh Market)* o si dari si afọnta awọn Akọwe ibẹ ni o gbe ri awọn ara Eko. Ọgbẹni S. A. Johnson *(Custom)* R. Akanbi Sumọla *(Custom)* F. C. John ati Olowu *(P & T)*, Puddicombe *(Treasury)* Rowland Taylor of Agbasa Town gbogbo wọn ni wọn si gba si ọwọ wọn s gba sẹsẹ, awọn Ọgbẹni wọnyi ṣe inawo Onjẹ ati mimu ni ojojumọ, Ọgbẹni John, Olowu ati Johnson wọn si nfi *Guitar* wọn mu wa ni ara ya nitori ajeji

ko mọ oju ilẹ, Akọwe Macaulay to ba Ọgbẹni Bright wa jẹ ẹniti o tun nfi waya ṣere on na si ntẹ pẹlu. A ko le rohin inu rere awọn enia yi tan, ki Oluwa ko mu wọn pada wa sile pẹlu alafia.

Ohun ti a ri ninu ilu Warri yi nipe onikaluku ni ilu tirẹ gbogbo ilu wọnyi lo ni Ijoye (*Chief*) ti wọn ẹniti o jẹ Olori gbogbo won (*Paramount Chief*) ni Chief Dore Numa awọn diẹ ni ilu na ni wọnyi:—1. Okere, 2. Agbasa, 3. Ẹpọn, 4. Ogberi Koko, 5. Efunrun, 6. Opete, 7. Ẹlẹrẹ, 8. Otokutu, 9. Egbo, 10. Magba, 11. Ogbe Ijoh, 12. Odogẹnẹ, (*Chief Dore's Town*) 13. Asagba 14. Dawodu's Town (iyẹn ni Ọgbẹni J. P. Dawodu ti Eko, ilu kan na ni won nfi oruko atijọ pe ni Alder's Town) 15. Wuogẹnẹ 16. Oparẹ, 17. Agbado, 18. Oto-gọ, 19. Jẹkota 20. Oviri, 21. Para, 22. Ovi, 23. Wokore, 24. Eru-Ele, 25. Egu-wo, 26. Ẹmẹwọn, 27. Ogunwe, 28. Wungun-Ẹran, 29. Wunmọna, 30. Jekri-Olu ati awọn ọpọlọpọ ilu miran. Awọn ilu wọnyi ṣaṣa ni eyiti a ko fi ẹsẹ tẹ, ṣugbọn iṣoro to wa nibẹ ni pe, ilu wọnyi buso kankan ni si ara wọn ọpọlọpọ ninu rẹ o ni lati wọ ọkọ sọda ni, awọn to sunmọ Barrack Native Court, Supreme Court, Police Station, European Firms ni, Ogbe Ijoh ati Okere awọn Loya to wa ni Okere Town ni Bucknor, Thompson, Egbe, Holm, Wright, Shyngle. Ogbe Ijoh Ọbafẹmi ati Pyne, Dawodus' Town Ate-Amonu.

Ni ọjọ *Monday* ni irọlẹ ni a gbọ iku Oyinbo kan ti o ku ti wọn si sin si sare awọn Oyinbo ni agbegbe Govt. School. Ni ọjọ kan ni iro kan ni pe Ọgbẹni Durowoju Akowe ni Prison Dept. Warri ku loju ona ninu *motor* ti awọn enia rẹ mu wa ni ati Abẹokuta wa gbe lọ nigbati amodi rẹ papọju ti titan si desi ni oju ọna. Awon Akọwe ẹgbẹ rẹ lo kọrin aro ni'le rẹ ni Warri nigbati wọn gbọ ajalu yi. Ohun pataki ti a tun ṣe akiyesi ni Warri ni ọja wọn ti won npe ni Ogbe Ijọh *Market*. Wọn ṣe buka na gẹgẹ bi Ṣabu ko si si gbogbo nkan ibẹ ti owo rẹ ko din si ti Ṣabu Oyinbo, awa bere wipe bawo lo ti ṣe ri bẹ, tabi wọn nra ti wọn lọwọ awọn igara ni, wọn ni ko ri bẹ, nṣe ni wọn nranṣẹ gbogbo nkan ti wọn ni ilu Oyinbo, on lo jẹ ki nkan wọn dinwo ku. Onjẹ ṣọgbọn wọn nilu Warri ti ki ṣe diẹ, on to jẹ pataki onjẹ Eko ni Gari, on to jẹ pataki fun pupọ awọn ara Warri ni (Starch) Taṣi ti awọn alagbafọ nfi si aṣọ ti wọn ba ro tan won afi ika meji to wọn a fi si ọbẹ wa ma wa gbọ foroforo bi igbati enia jẹ ẹkọ afala, lẹsẹkẹsẹ wọn ti fi omi sin sọhun, mo wa bere lọwọ ọmọ wọn kan wipe ki lo ṣe ti ẹ fi mu omi si kiakia, o ni bo ba lalẹ mọ ẹ ni ọiun ọrun lẹrọ. Ohun keta ti mo ri ni pe bi ọmọbirin ba jaja mọ ọkunrin ni ṣe ni wọn ma mu ọti ti wọn ma jo ṣule, ti ẹniti o ba gbọ orin ma wa wo ọmọbirin na loju wipe o ka re o ba ara rẹ jẹ inu awọn Obi rẹ a si dun, ọkunrin yẹn a san owo ponwun mẹta, ko si ni pe nitori o san owo, ki obinrin na di aya rẹ, ni ijọ *Wednesday* ijọ kẹrin oṣu *November* ni dede agogo mẹta ni Ọgbẹni Bright ati Macaulay gbọ ilu awọn Jẹkiri ni ẹhinkule wọn ni wọn jade ni wọn ri pe wọn ti mu nkan jẹ fun ọmọbinrin na, ti awọn enia rẹ si njo wọn wa bere wipe ṣe ọkọ rẹ ni, wọn ni ọkọ rẹ ko, ajeji ni o ni tọhun o wu lati kọkọ sunmọ o si ṣe bẹ wara were o san pọnwun mẹta, wọn ijọ to ba wun o le ma ranṣẹ pe ṣugbọn to ba ni oyun a san ponwun meji gbogbo wọnyi koi kan owo idana ati Ifẹnfẹn ara titun ti a ri ni ilu Warri ni eyi o. Ohun kẹrin ni pe ọna (*Roads*) to da lo yi ilu na ka, ọdan (*Fields*) si pọ janrẹrẹ, kakiri ilu, ṣugbọn bi ojo ba rọ ọna ti a nwi yi, ko ṣe gba rara nitori yanrin ni gbogbo titi na ko si okuta kan pẹnrẹn ninu rẹ. Omi tutu to dara lo yi ilu na ka, ko sisi omi buruku kan ni ilu na, omi liluwe fun ọmọde ati Agba wa kakiri ilu. Ile wọn ti wọn ngbe ko si botiri ni, ṣugbọn ikin ni wọn fi bo, a fi ile awọn Oyinbo, *Clerks Quarters*, ati diẹ ninu ile awọn enia pataki, ti ile ikẹn janrẹrẹ ni yẹn. Ko si ara ti awọn ara ilu Warri ko le fi Ọgẹdẹ Agbagba da, ni gigun iyan gẹgẹ, ni sise jẹ gẹgẹ, ni Agbagba didu o pa wọn ku a ko le sọ ohun ti a fi oju ara wa ri tan a fi ẹniti o ba lọ si ilu na. Aya Loya Percy Holm Iya afin ti orukọ rẹ nje Gloria Ọrẹ Williams ọmọ Ologbe Alade Williams pa ilẹ ijo mọ fun Adekunle Wright ni ile ẹjọ Kotu (*Court Hall*) ni won ma jo ijo na ni ojọ *Saturday* ijọ keje oṣu *November* 1925.

Emi ni ti yin nitotọ,
ATOLUGBOKUN.

---

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House,**

Import of General Lines

Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

## "IYAWO DUN LOSINGIN."

[ Lati owo ALAFOJURI. ]

Ariwo so lala lati ijo ọsẹ (*Sunday*) 8/11/25, titi di ọjọ ọsẹ 15/11/25, olubori ọjọ ni ijọ Alaruba (*Wednesday*) 11/25, ti o jẹ alẹ ijo ayisun—moju ọjọ Alamisi (*Thursday*). Nipa ọmọbinrin Wundiya awẹlẹwa fi dudu ṣola j gọdọ Miss Humuani Amọpe ti Ogboni wa Mustapha Gawa ti Ita Paşi *Street*, fi şe sara fun ọrẹ wa afinju wọ oja o rin gere Ogboni Surakatu Mustapha ti opopo Ita Ọbadina, *Street, Lagos*. Wo mi ọrẹ gbogbo gbajumọ ni *Muslims, Christians, Lawyers, Doctors etc.*, pe ṣọṣọ ni Ile Ọkọ Iyawo. Iya afin Ajibabi; Iriju Ọba wa Ibikunle Akitoye II Kabiyesi, o na kisa ninu Owo gbogbo Ijaye ti ile Eko tan si ibẹ, a fi gbajumọ ti a ko mọ ni Eko ni ọkunrin, ni obinrin ni a ko ri ni ibẹ. Ogboni Peter Jones ti *Railway Iddo*, ati *Lawyer* Ayo Williams ṣe kisa ni ile Ọkọ Iyawo ni alẹ ọjọ ayisun. Olubori ṣekan-ṣekan ni Baba wa Bakare King (Alewileṣe) lalayi ka Owo Fadaka, Poun kan ati Şile mẹwa ni o yọ ni agbo ti o fun Mọmọ Adetoro ati Jinadu onilu. Ariwo ta............wọn tun lọ fi abọ fun Baba wa yi ni ẹhin idupẹ, wọn rohin orişirişi Ọti olowo nlala ti o fi ki Ọkọ Iyawo pẹlu awọn Ẹgbẹ kabọ. O tun fi Poun kan fun Ọkọ Iyawo bọ wa ile. Bi a ba mu tiṣọtẹ kuro iru awọn Baba wa wọnyi ṣe ọwọn ni ọjọ ẹyẹ. Baba ni ile Baba ni ode Sanni Adewale Olori, ati Ogboni Belo Alufa ẹ ba wa dupẹ fun o, Oluwa ko si dupẹ ni ọwọ rẹ.

Ogboni Tiyamiyu Ọmọṣọ'a Savage, ati Mọmọdu Animashawun ati gbogbo awọn ẹgbẹ wọn, a ri yin ni ọjọ nẹ inu wa dun pupọ. Bẹbẹ ni ki a ma ri o. Ire a kari o. Mustapha Agunbiade Olori Bagan deji bẹni tirẹ ri, o duro ti ọmọ Ẹgbẹ girigiri o ko fi si ilẹ o na Owo o nara pẹlu, ori Ẹgbẹ na a gbe ẹ kalẹ o. Mọmọ Batula olori Ẹgbẹ, ori wa wu ni igbati a ri nyin o da bi ẹni wipe ka jẹ ọkan ninu ọmọ Ẹgbẹ nyin ni ijọ na. Mọmọ Adetoro iwọ njo kisa ajo gba Poun? Ọdọmọde kan tun jo ni ibẹ ti a ko mọ dada şugbọn a mọ ijo rẹ yatọ pupọ, Ilu rẹ ti a ngbo ni wipe "Ode dode Agbere, Ode dode Agbere" Ọrẹ wa Şafari Aromashodun, A. B. Lawal, Fọlawiyo, A. B. ati gbogbo awọn ti a ko le daruko tan, e ku aşeyẹ ọjọ. Amusa Rẹmi, Bakare o ku a şe yẹ o. Gbogbo Ja nmọ Oluwa ka ma yayin ni kekere Owo nyin aran. Ati Ogboniri iku Lasisi Adeniji.

A gbọ wipe Iyawo yege a gba fun. Ngbọ, şe Ọba Ibikunle lo tọ ẹ ati Iya afin Jironi Ajibabi. Ọgo ni fun Ọba wa Ibikunle ninu Ọla rẹ. Kabiyesi, ki Ọba ko pẹ. Ogboni Surakatu o di ano Ọba nu. Ẹ ba wa wa ọkan, awa na fẹ ba Ọba ati Ijaye tan; nitori ẹni Ọla ni wọn.

Baba Iyawo a ki nyin pupọ, Iyawo pẹlu Ọkọ agbadun ara wọn kalẹ. Aşẹ.

ALAFOJURI.

SECOND TIME IN NIGERIA.

## Onabolu's Art Exhibition.

The Exhibition consisting of Portraits and Landscapes in oils and in water colours, Pencil-Portraits, Black-and-white Drawings, Sketches, Posters and Designs, etc., by Mr. Aina Onabolu, in England, in France and in Lagos, including drawings by his pupils in various Schools in Lagos, was opened on Monday the 2nd day of November 1925, and will continue until Monday the 7th day of December, 1925.

At the opening of this Art Exhibition, prizes were awarded the sucessful pupils in Drawing-Competition.

Pupils, Parents, Friends and those interested in the development of West African Art are cordially invited to view Pupils' Drawings in the lower Committee Room of the Glover Memorial Hall free of charge.

Admission to the upper Committee Room, containing Mr. Onabolu's Paintings is by tickets obtainable at the door and Mrs. L. A. Archer, Marina, Mrs. Henry Carr, Tinubu Square, Councillor G. D. Agbebi, Folamobi House, Igbosere Road, Mrs. A. E. M. Gibson, Caxton House, Marina. Mrs. Lardner, Palm Church Street. Mrs. Tucker, Campbell Street. Nurse Ore Green, Campbell Street. Mr. & Mrs. Oduyoye, Bamgbose, and Alli Streets, and Miss Jibowu, Palm Church Street.

Season tickets entitling the Holders to 4 visits during Reserved Hours 5/-.

Tickets entitling the Holders to one visit during Reserved Hours 2/-.

Tickets entitling the Holders to one visit during Unreserved Hours 1/-.

Children's tickets 6d. Catalogues 6d. each.

## THE NEW WAY.

Has your child attained an age of six and still unable to pronounce from any Reading Book a word of one syllable? The Nigeria Cammercial Training Institute has discovered a new way of training such child not only to count, read, and write a word of one syllable in a comparatively short time without any further instruction after the knowledge of the alphabets, but also to march him into further field that invites conquest.

J. OLOYEDE DAVIES.

10, Balogun Square.

*N.B.*—Enrol for your Civil Service Entrance Examination to-day.

Mrs. Beckley of No. 53 Broad Street, begs to announce that she has started cake-baking of all kinds; ever ready to serve!

GUARANTEED

THE RALEIGH

FOR EVER



RALEIGH

THE ALL-STEEL BICYCLE

MILLER BROS. (L'pool) LTD.,

LAGOS.

**EKO AKETE**

Eko, Saturday, November 28, 1925

## AṢẸṢẸ JADE AKAN, A KO MỌ'BI T'O NLỌ.

Ede ti a le lo fun Gomina wa titun Sir Græme Thomson, K.C.B. leyi nitori ọna ẹ̀lẹ̀ ti o ti nmu pọn lati igbati o ti wọ'lẹ yi, fun iṣẹ ribiribi ti o wa niwaju rẹ; lati igbati o ti de lo ti nbẹ awọn Ile-iṣẹ Ijọba wo lọkọ̀kan, o lọ si *Post Office*, o lọ si *P. W. D.* eyini ni Ile-iṣẹ ilu, o lọ si Ile-iṣẹ *Railway*, o lọ si Ibudo awọn Ọlọpa ti Ebute Mẹta ati ti ilẹ yi ati orişirişi Ile-işẹ Ijọba miran. Awọn Panapana tilẹ fi ẹrọ kẹkẹ pipana wọn dabira fūn ni Ita Tinubu.

Gẹgẹ bi a ti gburo Gomina yi si, ki iṣe olobotò enia tabi ẹni ti ẹnu rẹ ndun kārā t'o ndun kōro: onişẹ papa si ni a gbọ pe o nṣe; bi ibẹwọsi rẹ yio ti ri nigbati o ba bẹrẹ si ṣa ni a koi mọ; gidipa, nigbati awọn Ẹgbẹ to ti lọ sogun ri, ṣe *Dinner* kan ni lọlọyi, ti a si pẽ sibẹ, nigbati a ni ki o sọ gbolohun ọrọ diẹ nipa awọn *Member* miran ti nwọn ko le wa, ko sọrọ kọkan ju pe "Ibà awọn ọrẹ wa ti ko le wa leyi" "*The Toast of our absent Friends*"

Awa Sanmọri to wa ni *Dinner* nṣepe pe "Ẹ sọrọ, Ẹ sọrọ" ṣugbọn Jagun ẹlẹ̀gba ọmọ Aṣẹyin ko sọ ju eyi lọ: eyi fi han ni pe Gomina na şi nwo oju ilẹ ni; a ko si le sọ bi ọwọ ti yio gbe yio ti ri, bi ọwọ lile ni o, bi ọwọ rirọ ni o. Baba nikan lo mọ; ohun ti o yẹ ilu nisisiyi ni ki a dẹ oju silẹ ki a bā le ri imu: o yẹ ki a pa gbogbo asọ̀ ija, ati irunu ti sapakan ki a si mã şakiyesi işisẹ rẹ.

Ẹ maşe jẹ ki a şe ara wa ni onigba lo npe igba rẹ ni akāra ti gbogbo aiye nfi ba ko'lẹ. Bi a şe ara wa ni aşọtẹ maru tabi arijẹ-ninu-ija, dajudaju oju eyi ni Gomina titun na yio fi wo wa, sugbọn ti a ba tun ara wa bi nipa yiye kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀ ọmọde şe, kọlọkọlọ "Sun suhun," yio jẹ ohun ti a dara fun ti kere ti kèrè wa.

Ẹwẹ̀, a bẹ awọn alaturu eyini ni awọn aturọta gbogbo, ki nwọn ma şe bẹrẹ si sọ ohun ti kosi si Gomina na lẹnu, ọpọlọpọ iıọ́ ni awọn Onişowo etekete, awọn Onişowo "Nwọn ni" bayi ti fi ba nkan jẹ ni'lu nibi ni akoko kan, ko si yẹ ki irufẹ hihọrọjọ bẹ̀ ṣọmọ lọwọ ẹnikẹni mọ: Aró, ẹ jare ẹ ma jẹ ki a şe ara wa ni eni palanta nipa gbogbo ohun ti a tọka si loke nibi.

Nitotọ, a ko le ri ohun kanna, papa ọrọ ilu dogba-dọgba, şugbọn eyi ko to ki a fi aileri nkan dọgba bẹ̀ şe Aşitani sarin ara wa, Gomina titun şi jọ Alejo ti o loju şugbọn ti koi le tete fi oju na riran, ọwọ ẹnyin ilu lo ku si bi ẹ o ti şe le şo Gomina na ni "tẹ̀tẹ" ki a ba le şe iranwọ fun lati ba ni jumọ ri ohun pupọ ti Ilu nfẹ nisisiyi fun alafia awa enia inu rẹ.

A tumba o!

---

## GBOGBO AIYE NGUN ẸṢIN EKO NGUN ARUKỌ. – ARA WA L'A NṢE!

[*Lati ọwọ* Kekere Ilu.]

Si Oniwe-Irohin *Eko Akete.*

Iba o!

O şẹ su enia lati ma ri nkan mi sọ ju a nl'agogo ọtẹ ati tẹmbẹlẹkun lọ. Ariwo ati giri-giri ọsẹ to kọja şe enia l'anu pe bi a ti n..i i, ti a nsa to yi awọn mi şi wa ti nwọn ni awọn ko yi mọ eni to ku.

Njẹ ko yi ti to akoko ti a o ronu wo ki a ye nidi ija, ọtẹ, iregbe, inunibini, ati rikişi?

Ibosi a bo bo Ọba Eleko titun ti a ngbọ, ti a si nka, ko fun ni ni ibalẹ aiya arara. O si buru pupọ lati ri işẹ ti awọn kan pete ati şe nidi rẹ. O tọ, o si yẹ pe ki t'ẹru-t'ọmọ sun kaka şori ọran Eko lati ba yi iwa pada ki ilu le toro fun anfani gbogbo enia to wa l'Eko ati ilu iyoku ti o wa ni *Nigeria.*

Gẹgẹ bi olu o to asiko ti Eko tun pi lati bẹrẹ si şe aşaju fun awọn Ilu okẻ. Eko ti ba nkan jẹ pupọ sẹhin. O tọ ki a bẹrẹ si tun u şe. Şugbọn ire kan ko le si nigbati ọtẹ ba ngba, to si nran, lati ọjọ kan de ekeji.

Niti ọrọ a dojuti Ọba titun. O yẹ ko ye gbogbo wa pe ati ọtun ati osi, t'olori t'elesi, ni ko yi şe

ẹtọ. K'a kọ sọ ti awọn tó nho. Olotọ to'si fẹran ilu rẹ ni lati mọ pe lati ho bo ẹnikeji on, ki a ma ṣẹṣẹ wipe Ọba (l'ọna kona to le gba jẹ Ọba na) ko dara, ko si ṣe rere kankan fun ilu, nipataki gẹgẹbi ode na ti nri n s siyi. Lai si ani-ani, ti nkan ba rin l'ọna tara, to lọ ni eto, Akitoye ki nṣe ẹni ti a le wipe ko le de ile Oye Eko. Ohun to padi rẹ lo ṣe e ni ẹniti Ilu ko fẹ gba. Ṣugbọn bi ọrọ ti lọ, ati bi ifẹ Ijọba ti lọ si, ko yẹ ki a taku wọnle pe a o ni ba a ṣe ṣa na ni. A ba ṣe, a ko ba a ṣe, aidara lo jẹ lati ho bo o ni ode. Bi Ọba ti inu ilu ko yọ si ba nlọ a le maṣe bi ẹni ri i, ṣugbọn ti o ba re kọja iyẹn o ndi ọwọ iwọn. Ọba to kọja ti a ko buwo abuku nla ni. Ṣugbọn iyẹn ko ṣe ja si ita ni aja-jare. Hiho buru, ko si tọ ni ilu bi Eko ti awọn agba rẹ ko mọ iṣe agba iṣe. On ti a nsọrọ le lori ni yẹn.

L'ọwọ keji. Awọn isọngbe ati alaroti Ọba papa fẹ huwa ti yio mu ilu toro ti yio si jẹ ki Ijoba ilu rin laisi idiwọ. Lati ọjọ ti nwọn ti ṣẹgun l'ọna ti nwọn fi ṣẹ na, ti nwọn ba nwa ire Eko ni, nwọn ti to fa ilu mọra. K'a duro ni iduro pe "ṣe Ijọba wa fun wa na, tulasi gbogbo nyin lo ni lati wa tunba ati lati sin, bi ẹ fẹ bi ẹ kọ" ko fi ọgbọn iṣelu han. Ọna Yoruba kọ ni iyẹn. Kini nwọn tun nfẹ. Nwọn ti ṣi ba Eleko ti gbogbo Ilu wa fún, nwọn si ti gbe ẹni to wun wọn de ipo rẹ. Ki lo tun ku ti nwọn ko le fi lakaye fa ilu mọra ki ilu le gbagbe ara? Nwọn wa ro pe larin Ofin Ijọba le fi agbara mu Ilu sin ẹniti Ilu ko fẹ? Wukuwuku ti ko gbede lasan mọ pe iwa "ko tan ni idi nyin na" ko le mu inu ilu yọ. Ọwọ tutu, ahọn tutu, aniyan, ko ba ti ṣe iṣẹ ribiribi to bẹ gẹ ti idaji tabi ju bẹ lọ ni Ilu yio ti di ti Ibikunle. Ṣugbọn ijo Ṣẹkẹrẹ ati orin owe, ana ṣifila, iwe-ebu ati ti yiyọ, ṣe on ni nwọn fi ten ilu ṣe? Ẹni ti a nyọ, tabi ti a fi ndapara, ti a nbu, ti a fi nrẹrin le ri ni ko yọ mọ ni? Iwa bẹyẹn ha le ran ilu lọwọ? O tọ ki awọn alabaṣe Ibikunle yi iwa pada, ki nwọn fi rikiṣi ati inunibini silẹ ki ile Oye Ọba le san a. Eyi ti nwọn nṣe lo tubo nran ibinu to ti wa ni ilẹ. Ki nwọn kogba rikiṣi sile, ki nwọn si ye wa ọran si awọn Oloye Eṣogbayi l'ọrun, nitori igi oro ni iyẹn nlẹ. Eyi ti nwọn ti lẹ silẹ ti buruku fun ra rẹ. Alumọ yio jẹ ko tubọ buẹkẹ ni. Nigbati a ba ti ri ohun ti a nwa a ki tun fọwọ ara ẹni ba a jẹ mọ. A npurọ mọ awọn kan, a nbu abusọ, a ndi rikiṣi a nṣe ọna ti Ijọba yio fi rọ awọn kan l'oye k'o si le wọn lọ, ko le bi ọmọ alafia. Iga ti a ṣe iru rẹ si ko le duro ti ni, bẹ ni ko si le ba ni ṣe. Ẹ jẹ ki a fi ọwọ ẹrọ mu ọrọ atunṣe ki gbogbo nkan le toro.

Oju nti awa ọmọde ilu fun iregbe ati ọtẹ aṣe-isinmi. Awa nikan kọ ni ilu, ti wa yi kele ju. O bu-aiya.

Ki a to pari iwe wa yi a fẹ lati bẹ awọn Ọmo-Ibiga ati Ibi-lẹ ki nwọn wariko lati le mọ bi irẹpọ yio ti ṣe le wa ni Isalẹ-Eko. Ọran yi ki nṣe ti nwọn nikan nitori o kan gbogbo wa, t'onile t'alejo. Ṣugbọn ọwọ wọn lo gbe wa nitori awọn ni nwọn ni Oye Eko. Bi wọn ba fẹ ki Eko san gbogbo wa, ki o jẹ Ilu-atata gẹgẹ bi o ti wa ri, ki nwọn jọwọ yanju ọro larin ara wọn. Ija wọn ni nisisiyi. Ti awọn Kiriyo diẹ ni. Ti awọn tikalawọn ba dide si nkan wọn, ọna ti gbogbo rẹ yio fi tu, k'o ba, Ọlọrun yio fi han wọn.

Oyinbo ko fẹ mọ. Gbogbo ija wa, ara wa l'a fi nṣe. Edumare yio to o!

KEKERE ILU.

---

## Congratulations.

The following West Africans appear in the list of successes :—

Mr. S. Ayodele Thomas, passed 2nd Class, Roman Law ; M. A. Shorinola Siffre, passed 3rd Class Criminal Law and Procedure ; Mr. Thomas Ekundayo Williams, passed 3rd Class, Real Property and Conveyancing ; Final Examination Class II Gibril Martins ; and Class III Felix Olalunde Vincent

## Mr. E. A. Bright.

Mr. E. A. Oluyele Bright, Head Clerk, Works Manager's Office, Ebute Meta, who has been touring Kano, Jos, Ile Ife, Ondo, Ilesha, Zaria, Jebba and Bukuru, arrived Lagos on Wednesday the 25th of November, 1925, by Kano Train. Ẹ ku abọ.

## His Excellency the Governor on Tour.

His Excellency the Governor, Sir Græme Thomson, K.C.B., will entrain at Iddo to Kano on Tuesday, the 1st day of December, 1925, at about 7 p.m.

---

The marriage took place on Thursday the 26th instant at Holy Cross Cathedral (Roman Catholic) between Mr. Olayemi Abiodun Abayomi, B.A., Barrister-at-Law, and Miss Claudina Carrena, daughter of Mr. and Mrs. A. E. Carrena of Bamgbose Street, Lagos, at 2.30 p.m.

---

The marriage of Miss Felicia Ayodele, daughter of Fred. Williams (late) of Agege, with Rev. Theodosins Oluwole De ẹke, B.A., is announced to take place on the 10th December, St. Jude's Church, Ebute Meta, at 10 a.m. To S. A. Sogbesan, Esqre., ẹ ku pamọ

---

Also African Parlour Marriage took place at the house of J. K. Coker, Esq., Planter of Agege, of Miss Esther Omoriọ-ọla, daughter of Mr. Samuel T, Coker, on Thursday the 26th November, 1925, with Rev. Joseph Adefarati at 10.30 a.m.

OLUṢAKIN.

---

## KERE O!

Iya-afin Mrs. Beckley nsu Akara didun (*Cake*) ta nile rẹ, ni 53, Opopo nla, õ gbeyawo ni o, rẽ yan tirẹ nibẹ; o sami fun ọmọ ni o, rẽ yan tirẹ nibẹ; o tọrọ ọmọ ni o, re yan tirẹ nibẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo rẹ.

## IROHIN ABẸOKUTA.

### IGI MA DA O! KI OLUWA FI ỌRAN MỌ BAYI O!!

Ko si bi o ti ri ni nigbati a gbọ ewu mọto ti o wu ọpọlọpọ enia ni Satide ọjọ kọkanlelogun oṣu yi.

A gbọ pe awọn ti o f'arapa ninu mọto No 162, ti o jẹ ti Ọgbẹni S. O. Biobaku ti o nṣiṣẹ fun awọn Onişowo *African & Eastern Trade Co.*, ni Ibara na to bi mẹjọ. Gbogbo nwọn si wa labẹ itọju Onişegun, *Ẹgba Native Administration*.

Ki awọn awa-mọto wa ṣe pẹlẹpẹlẹ o, ki awọn onimọto wa ṣọ enia gba fun mọto wọn, nitori abẹbẹlubẹ enia ko yẹ fun mọto wiwa papa ninu mọto ti ogidinleje enia yio ko ara wọn jọ si, bi igbati a ko Sadinni sinu panu.

Ẹnyin ti ẹ farapa, Oluwa ko ni jẹ ki o nipa o, fun ẹniti o ni mọto *Reo* titun yi, ki Oluwa fi ofo r'ẹmi o. Lọwọ bilisi on alusi gbogbo, ki Oluwa rere ma gba wa. *Amin.*

Ohun meji ni mo tọrọ lọdọ rẹ............mu asan ati eke jinna si mi; maṣe fun mi li oşi, maşe fun mi lọrọ; fi onjẹ ti o to fun mi bọ mi.—*Iwe Owe Ori 30. Ẹsẹ 7 ati 8.*

Eyi ni ọrọ Iwasu Ẹni-ọwọ J. Pearse Alufa Ijọ St. Jude's ni Ebute Mẹta, ni ọjọ Isin Ikore ti Ijọ St. Peter's Ake, ni Abẹokuta, ni Sọnde ọjọ kejilelogun oşu *November* yi, 1925.

Jagun wa boto. Ori gbogbo awọn ọmọ Ẹgba patapata gba ti o wa labẹ Iwasu ajini-pẹpẹ yi, lo ji pẹpẹ. Tobẹ ti o mu ẹnu kan Aga Ikawe ti o wa ninu Şọşi na pe ko tun ba işiro mọ, pe o yẹ ki Şọşi yi ni eyiti o wa l'ode nisisiyi, ti o jẹ alaworan Angẹli ti o jẹ ojulowo Idẹ faufau.

Ko ma ti i sọ tan, Ọba wa t'o mọ'yi t'o m'ẹyẹ Ademọla Keji, Alake, ni on yio ra fun Ijọ Ake, ki o to to akoko *Easter* ti mbọ lagbara Baba.

Owo ti yio mu Ikawe Alangẹli yi de lati Ilu Oyinbo ko ni din ni igba pọnwun (£200).

Kabiyesi, Ọba Alake, Ọmọ Erin J'ogun ẹla, Omọ Ọtẹnkan, Kabiyesi! Kabiyesi!! Ẹ ku inawo, ọwọ nyin yio ma r'oke o. *Amin.*

Ninu eso Iwasu Ẹni-ọwọ J. Pearse na tun ni Idẹ ti o wa lori Aga Iwasu ti awọn Alufa ima gbe Bibeli le l'ori, ti yio jọ alaworan Idi, ti Dokita Akilawọn Adefolu şe ileri fun Ijọ. Eyi ko ni din ni pọnwun mejilelogun (£22) lati Ilu Ọba Oyinbo wa.

Ki Ọlọrun ma ran Dokita yi lọwọ ti o nfi apẹrẹ rere lelẹ fun awa ọdọmọde-kunrin lojojumọ. Dokita yi li o jẹ ki owo Ikore wa to bi o ti to yi l'eşi.

Apẹrẹ rere ni eyi fun iwọ ọkawe yi, ati fun emi papa.

Owo ti a kojọ l'aro ati Isin Ọmọde l'alẹ le ni (£109) pọnwun mọkandinladọfa. Bi a ba si fi ileri owo ti ọdọ Ọba wa Alake ati aburo rẹ Dokita Akilawọn Adefolu mọ ọ (Iwasu Isin Ikore Ẹni-ọwọ James Pearse lo sa nu u wa) ileri t'ọtun t'osi jẹ (£223) ẹ ko mọ iye ti o ku si?

Ọpọlọpọ ẹgọrọ ọkan Ikore lo tun wa, ati ọpọlọpọ Ẹgbẹ li o tun ku ti nwọn koi ti mu ọkan ohun Ikore wọn wa.

Ki Oluwa Ikore ki o bu si apo olukuluku nyin o.

Ẹni-ọwọ James Pearse ajisọdidun mo gbadura rẹ o, ki Ọlọrun fi ẹmi gigun jinki rẹ, ki a le ma ri o pe wa ji wa pẹpẹ o. *Amin.*

Awọn Alufa ti o pesẹ sibi Isin Ikore na ni:—

Ẹni-ọwọ J. J. Ransom-Kuti
,, James Pearse, ti Ebute Mẹta,
,, E. K. Ajai-Ajagbe, ti Ọgbẹ,
,, N. O. A. Morgan, ti Iporo Ake ati
,, T. O. Dedẹkẹ ti Ode Ondo ati ọpọlọpọ ojulumọ gbogbo lati Eko, Ibadan ati orişirişi Ijọ wa.

Ki Oluwa jẹ ki a le şe eyiti o ju eyi lọ ni ọdun ti mbọ o. *Amin.*

Emi ni ti nyin nitotọ,

AWODI OKE.

---

## NI IRANTI

'Arakọnrin mi ọwọn,

**MR. B. B, ỌKỌYA**

(*ti District Traffic Superintendents Office, Kano Station, N.P.*)

Ẹniti o pa ipo da ni Ogunjọ oşu *November, 1925.*

1. Ẹniti ma tọju Ará
   Ẹniti ma şikẹ Ọgba
   O re 'nu itẹ Ogo.

2. B. B. Ọkọya bọ lọwọ aiye
   O bọ ninu oşi
   O re 'nu itẹ Ogo.

Eko,
25.11.25.

# SERVICE COMPANY.

## ẸGBẸ AFÒWÒ SINNI.

P. O. Box 169,
Broad Street,
LAGOS.

Ọgbẹni tabi Iyãfin,

A fẹ lati kéde fun gbogbo awọn enia ti nra oniruru tabi orişirişi ọjà tita pe awọn Ẹgbẹ ti a npe ni *The Service Company* le ta ọjàkọ́jà ti ẹnikẹni ba nfẹ rà ni owó pọkulọ. ojulowo ọja ni nwọn o si ra fun wọn, ti nwọn o si fi ranşẹ si wọn pẹlu.

Eko ni ilu ti gbogbo enia si gba pe o jẹ amu (ilu) fun ọja tita ati òwo-şişe. A si fẹ sọ, bi ẹniti o ti lọ siwaju ninu òwo-şişe pe, a o tubọ jẹki ère òwo rẹ tubọ lọ siwaju ati ki awọn onibara rẹ si pọ. Gbogbo ọja ti a nta, ti a si fi nşowo ni mbẹ lọwọ wa. Nigbakugba ti o ba si jẹ pe ọja tan lọwọ wa, (eyi kĩ sĩ fi igbagbogbo ri bẹ̃, afi bi ọja ba jẹ eyiti a dura lẹkanşoşo) a le ra nibomiran fun nyin ni ilẹ yi ni owo ọpọ̃. A si le ranşẹ fun u ni Ilu Oyinbo pẹlu.

ỌNA TI A NGBA BA ENIA ŞOWO.

Fi owo ati iwe ọja ti o nfẹ ra ranşẹ si wa, ati owo diẹ fun inawo Òtẹ Ọba, ati owo ọkọ̀. Owo ti o ba si şiku, a o şiro rẹ sinu iwe wa fun ọ, tabi ki a fi owo ti o ba şiku na ranşẹ si ọ.

A le fi owo ranşẹ si wa lati Ile ti a nfi Iwe ranşẹ kakiri (*Post Office*), nipa sisọ ọ di owo *Paper* wọnyi :—*Money Orders, Postal Orders, Bank Drafts* tabi *Currency* (bi o ba si jẹ *Currency* ni, ki a *register* rẹ).

ỌJA IPOLOWO.

A le fi ọja bi iwọn pọun meji, mẹta, tabi marun ranşẹ si awọn ti o ba şẹşẹ fẹ bẹrẹ owo-şişe. Iwọnyi yio dabi ọja ipolowo, iru eyiti a ba ro pe o yẹ li a o si fi ranşẹ. Òwo daradara ni ẹniti o ba kọ fi ọja wa şẹwọ yio mã şe. Gbogbo agbara ti o si wa ni ipa wa ni a o sa lati şi awọn ti o ba fẹ ba wa şowo lori.

ỌNA TI A O MA GBA FI ỌJA RANŞẸ.

A o ma fi bi owo ọja ti nlọ soke lọ sodo si ranşẹ gẹgẹbi a ba ti ri iwe ẹnikẹni gba lati *Post Office*, tabi ki o ba tubọ le yá, ki a ma fi waya ranşẹ eyiti a ti san owo esi rẹ tẹlẹ. (*Reply Paid Telegram*). A o si ma fi waya ọfẹ sọ bi owo ọja ti ri, nigbakugba ti a ba ri waya ti a ti san owo esi rẹ şaju gbà.

Bi ẹnikẹni ba si nfẹ lati tẹ ohunkohun nipa işẹ rẹ, inu wa yio dun lati mọ bi iru ohun ti o ba fẹ tẹ na ti ri.

Ã sìn o!

THE SERVICE COMPANY.

*Cable Address:—*
"QTAOROJU" LAGOS.

KARIMU KOTUN,
P.O. Box No. 505.
3, Docemo Street,
Lagos, (Nigeria.)

**"Indents House."**

Import of General Lines, and Export of Produce Commission Agencies undertaken, Correspcndence Invited.

The West African Soap Co. Limited
APAPA, NIGERIA

*Manufacturers of*

NEPTUNE
PALE SOAP

BUGLE
PALE SOAP

MAGNET
CARBOLIC SOAP

will send Price Lists and terms to merchants upon application to

P.O. Box 522
Lagos
Nigeria

F 323

TO THE GOVERNOR FROM THE SECRETARY OF STATE FOR THE COLONIES:—

I.

Your telegram dated 21st November. His Majesty the King commands me to express to you and to the people of Nigeria sincere thauks for message of sympathy

II.

*24th November.* Death of Queen Alexandra. Official funeral service will be held 11.30 a.m. Friday. Westminster Abbey. Private committal Windsor following day.

III.

*24th November.* In connection with death of Her Majesty Queen Alexandra, War Office has despatched following telegram, 21st November, to all military commanders at home and abroad, begins: "All flags at flag stations will be flown at half-mast from to-day until day following date of Queen Alexandra's funeral. Issue instructions for officers to wear mourning band until further order. Drums to be covered with black; crêpe to be hung from top of colour staffs Infantry, and from standard staffs and trompets of Calvary"—ends. Appropriate instructions should be given by you in connection with West African Frontier Force.

---

It is further notified for general information that a Memorial Service for Her late Majesty Queen Alexandra will be held in St. Paul's Church, Breadfruit, Lagos, at 8 a.m. on Friday, the 27th November. Officials who are present should wear uniform, if entitled to do so.

By His Excellency's Command

F. M. BADDELEY,
*Chief Secretary to the Government.*

Chief Secretary's Office,
Lagos, 25th November, 1925.

*Extraordinary Gazette 25/11/25.*

**See Fancy!**

Ladies' L. O. Trimmed Hats, Crepe & Georgette Hats, Shoes, Japan Silk Stocking & Shawls Underwears, etc.

Gent's Real Velour Hats, Felt Hats, Lhoes, Shirts Socks, Ties etc.

Boys & Girls Dresses, Shoes, Bonnets, Silk Panama and Felt Hats.

Also all classes of Bicycle accessories

Cheap : Cheap : at

OLUFUNMI STORE:
42, Kano Street, Oyigbo Market,
(*opposite Miller Brothers*)
Ebute Metta.

## IROHIN ODE ONDO.

### ISIN IKORE.

Akoko yi jẹ akoko ti a nmu awọn nkan ti a ri mu lati inu oko wa siwaju Ọlorun lati fi ẹmi ọpẹ ati imore han fun oniruru ipese ohun rere gbogbo ti Ọlọrun fi nṣikẹ awa ẹda ọwọ rẹ. Ninu oṣu *October*, Ẹni-ọwọ S. C. Phillips M.A., ẹniti o jẹ Alabojuto gbogbo Ijọ agbegbe Ondo ati Ẹni-ọwọ T. O. Dedẹkẹ B.A., Alufa Ijọ St. Stephen's Oke Aluko, jumọ lọ si Etido (*waterside*) lati lọ ṣe Isin Ikore larin awọn Ijọ Ondo ati Isobo ti nwọn wa nibẹ, nwọn si pada bọ ni ipari oṣu na pẹlu irohin ti o ṣini lori pupọ nipa ẹmi ilawọ ti awọn enia fi ṣe Isin Ikore wọn ni oniruru Ijọ. Ni ọjọ kini oṣu *November*, a ṣe Isin Ikore ti St. Stephen's ti o jẹ Olu Ijọ gbogbo agbegbe Ondo, Isin na ṣini lori pupọ, awọn Ẹni-ọwọ S. C. Phillips M.A, M. C. Adeyẹmi B.A., ati T. O. Dedẹkẹ B.A., ni o ṣe akoso isin, Ẹni-ọwọ S. C. Phillips ni o ṣe Akanṣe Iwasu nipa Ikore, Oloye Ṣaṣẹrẹ ati awon jakanjakan miran wa nibi Isin yi ile kun ọna si bo fun ọpọ enia. A kan sara si awọn Ẹgbẹ Akọrin ati Aluduru Ijọ St. Stephen's fun orin wọn ti o ja gara ni ọjọ na ati awọn (*Sidesmen*) Atọkun Ijọ fun eto daradara (*order*) ọjọ na. Ki Ọlọrun jẹ ki ti ẹmiran ṣ'oju ẹmi wa o. *Amin.*

### AWỌN ẸGBẸ SCOUT KẸTA TI ONDO
(*3rd. ONDO TROOP*).

Awọn Ẹgbẹ *Scout* kẹta ti Ondo dabira ni Ọgba Ile'we Giga ti Ondo ni Idimoge ni ọjọ 29 oṣu *October*. Ọjọ yi jẹ ọjọ ti nwọn nṣe iranti igbati o di ọdun kẹta gbako ti nwọn ti bẹ ẹ Ẹgbẹ *Scout* ni Ondo. Ajẹlẹ Ilu Captain P. E. M. Richards ati Igbakeji rẹ A.D.O. ati ẹpọlọpọ awọn gbajumọ Ilu wa sibi ere yi. Ohun kini ti nwọn kọṣọ ṣe ni "iba *Scout*" (*opening ceremonies*) lẹhin na nwọn ṣe iba fifi aṣọ wọ awọn *Scout* ti o ṣẹṣẹ gbaṣọ, lẹhin eyi nwọn ṣe oniruru ere *Scouts* ti o wu ni l'ori pupọ. Ni ipari ere, Ajẹlẹ ba awọn *Scout* ati awọn ti o wa worän sọro nipa ohun ti Ẹgbẹ *Scout* jẹ, ati bi o si ti jẹ Ẹgbẹ ti o wa kakiri gbogbo agbaiye nisisiyi ati pe o jẹ ohun ti o yẹ ki gbogbo ọdọmọde ni ẹ nitori Ẹgbẹ na nkọ ọmọde ni iwe rere. O yin Ọga awọn *Scout* na (*Scoutmaster*) fun äyan rẹ lori Ẹgbẹ yi nigba-gbogbo, lẹhin ẹyi awa kọ "ki Ọlọrun da Ọba si," awọn *Scout* si wa fi idaro wọn "*Eengoyama*" tuka. A-ṣeyi ṣ'ẹmiran o.

### OLUDANWO ILE-ẸKỌ.

Oludanwo Ijọba (*H. M. Inspector of Schools*) t' le si Ilu lati ọjọ kọkanla oṣu yi, o si ti bẹrẹ si dan wọn Ile-ẹkọ ti arin Ilu wo. Awọn Ile-ẹkọ ti a ti si ahẹ Ijọba ni Ondo ati agbegbe rẹ nisisiyi to marun nitorina Oludanwo yi yio lo to ọṣẹ melo kan nibi.

### ẸGBẸ AGBẸ (*FARMERS' ASSOCIATION*).

A ti da Ẹgbẹ yi silẹ ni Ondo nisisiyi ṣẹ nto ọdun meji gbogbo awọn Agbẹ patapata ti wọn ni ọpọlọpọ oko koko ati obi gbanja ni agbegbe Ondo ni o wa ninu Ẹgbẹ na. Awọn Ijọba ni o da Ẹgbẹ yi silẹ nibi gẹgẹbi ti Abẹokuta, Eko ati ibomiran ti nwọn si nṣe ayan lati kọ awọn Agbẹ wa ni ọna ati ma fa mẹnti ati lati gbin oniruru nkan, a ko le ṣalaima ma yin Ọgbẹni M. C. Adeyẹmi Ọga Ile-ẹkọ Giga ti Ondo fun ayan rẹ lori Ẹgbẹ yi on lo jẹ ologiri ti o ba ni di Ẹgbẹ Agbe Ondo mu, bẹni a si ni lati yin Ọgbẹni S. R. Fadaṣe ẹniti o jẹ akọwe awọn Ẹgbẹ yi fun iṣẹ ribiribi ti o nṣe. Ẹgbẹ na dara pupọ gbogbo awọn ti o wa ninu rẹ si jeri pe awọn ri iranlọwọ pupọ nipa rẹ. A gbọ pe nwọn nṣe eto ati ṣe ifihan oniruru nkan oko (*Agricultural Show*) ni ọjọ 28 oṣu yi ni oke ile Ajẹlẹ Ilu ati pe Oyinbo ti nṣe Alabojuto nkan oko ati awọn Oyinbo miran yio wa lati wo awọn nkan ti o ba dara ju ati lati fun wọn ni ẹbun.

A ni ireti pe eyi yio mu iṣiri pupọ wa fun awọn Agbẹ, yio si mu ki a tubọ tẹ'pa mọ iṣẹ ati ma ro ilẹ ti Ẹlẹda fi jinki wa.

ẸKIMOGUN.

## Thanks for Sympathy.

Mr. M. T. Ogumẹfun and family beg to return thanks to all who by personal call, Letters and Telegrams sympathised with them in the irreparable loss they have sustained in the home call of their dearly beloved wife, mother, sister, and cousin Mrs. Frances Lydia Ọlayinka Ogumẹfun on the 11th November 1925.

### IROHIN KANO.

Ni alẹ ijọ 19/11/25 ni Ọgbẹni B. Ọkọya ti ib' iṣẹ Reluwe jalaisi ni *Hospital*, ni ọsẹ to kọja ni a gbọ pe Ologbe yi bẹrẹ aisan. Ki Oluwa ki o ma ṣai tu aya ati awọn Ebi rẹ ninu.

Tayọtayọ ni a fi ki Mrs. Victoria Beckley aya Ọgbẹni Ladipọ Beckley kabọ, ẹniti o ti lọ sile fun Ibẹwo Iya wọn agba, "*Sonu da sua mala Belo.*"

A ba Ọgbẹni E. A. Oshun (*Tailor*) kẹdun fun ọmọ rẹ obinrin kekere to ja'aisi ni 18/11/25, ki Oluwa fi mọ bẹ.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

CATHOLIC.

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yio ṣe Isin ni gbogbo ẹkoko wọnyi. (MORNING)
Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.
(EVENING.)
(Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.
ST. MICHAEL'S ) Lafiaji.)
MORNING. 7—8 8.30—9.30
EVENING. 5.45—6.30

ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church, | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | The Archdeacon |
| 6.30 p.m. | | The Curate |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. S. V. Latunde |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. W. O. Aiyedun |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. H. Ogunro |
| 6.30 p.m. | do. | do. |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. L. R. Potts-Johnson |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Ereko | Bro. C. B. Williams |
| 3 p.m. | | Bro. J. C. Lewis-Lisk |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | | do. |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Bro. C. W. Faukner-Shaw |
| 7 p.m. | do | Bro. E. E. Ajọṣẹ |

Williams' Memorial Wesleyan (Ebute Mẹta)

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. J. Oyegbọla |
| 7 p.m. | do. | Rev. D. A. Babubunmi |

AFRICAN

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Revd: John F. Ogunko |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | Christ Church (Ebute Mẹta) | |
| 5.30 p.m. | | |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. Adeọla Abọyade-Cole |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. J. Ṣotayọ Williams |
| 9 a.m. | Zion | |
| 6.30 p.m. | do. | |
| 9 a.m | Salem Church (Ebute Mẹta) | |
| 5.30 p.m. | do. | |
| 9 a.m. | Bethlehem Church (Ebute Mẹta) | |
| 6 p.m. | | |

| | | |
|---|---|---|
| 10. a.m. | African Methodist | Bro. J. K. Coker |
| 7 p.m. | do. | Bro. E. A. Amusu |

BAPTIST

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ebenezer | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Ararọmi | Rev. A. A. Puddicombe |
| 6 p.m. | | do. |

ISHOLARIAN.

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Bro. S. A. Coleman Daniel |
| 7 p.m. | | The Founder |

EPISCOPAL

| | |
|---|---|
| 9 a.m. & 4 p.m. | Patriarch J. G. Campbell |

AHMADIA

| | |
|---|---|
| 6 a.m. | Fajir Service Y. P. O. Ṣedẹinde |
| 5.30 p.m. | Open Air Service Imam K. R. Ajọse (Central Mosque, Arọlọya Street.) |

ZION CONGREGATIONAL

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Kakawa St. | Locum Tenens |
| 7 p.m. | do. | do. |

ARMY

10 a.m. Glover Memorial Hall
Capt. Jones and the cadets.
7 p.m. do.

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m. Opne Air Service at Campbell Square, J. P. A. Taylor

AFRICAN FAITHIST KOSMON

5 p.m. 8, Shitta Street. The Chief Ironupiwada (Ebute-Awo)
10.30. a.m. Pastor J. A. Agbeniyi
3.30. p.m. (Harvest) do.

## IGBẸ L'OWO WÀ

### EKO.

Bi òwò Ekurọ, Epo ati *Cocoa* ti kusi ... ọsẹ yi leyi:—

EKURỌ
£15 12 6 fun *ton* kan
EPO.
£25 10 fun *ton* kan.
COCOA.
£27—£28 fun *ton* kan.

### AGEGE.

COCOA
£28—£30 fun *ton* kan

### Kano.

GROUND NUTS
£11 15 0—£12 fun *ton* kan.

"O di ọdun marundi-logoji nisinsinyi ti a ti bẹrẹ si ṣe *Mentholatum*, a si mọ ọ kakiri gbogbo aiye bi egbogi ti o wulo fun wiwo:—Otutu oriṣiriṣi, Ọna-ọfun ti o ndun-ni, Ori-fifọ, Arun Awọ-ori, ati gbogbo Arun Awọ-ara."




A HEALING CREAM

# Mentholatum

Mentholatum has been manufactured for 35 years and is known throughout the world as a medicine of great value for Colds, Sore Throat, Headache, Scalp Troubles and all skin ailments

**THE MENTHOLATUM COMPANY LTD., SLOUGH, ENGLAND.**

*Over 16 million jars sold last year.*

## J. C. VAUGHAN

Ti ile-ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọn i şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna: bi o fẹ da awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ra nibẹ:

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹgẹ l'oşe fun ọ lati 're yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kanna.

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Atari-Ajanaku lọjọ to ti pẹ: bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai! bi o ri orişirişi Ọkọ ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwo Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere ibẹ.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

RICHARD A. AJAYI,

*Fashionable Tailor.*

21, Moloney Bridge Street, Lagos.

Come for trial. Fitting Guaranteed

Charges very moderate.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete.*

---

## Saccharine! Saccharine!! Saccharine!!!

*Purer than Sugar, Sweeter than Sugar, Cheaper than Sugar and more economical than Sugar.*

Try it in your Cup of Tea Coaca, Coffee or in your Oats or Paps, you run no risk.

Saccharine is absolutely harmless even to the most delicate system; it is very good for young and old, it is now in use in many homes. "A boon to those who do not take Sugar and to travellers." If you are in doubt consult your physician.

1 Bottle of 600 Tablets for 1/3d.
1 " " 500 " " 1/-

*Good Bargains.*

Apply to the Manager:—

APALARA STORE,
72, Great Bridge Street,
Enu-owa.

P.O. Box 772,
Lagos, Nigeria.

---

## TO LET OR LEASE.

All that piece or parcel of land with the buildings thereon situate at 106, Denton Street, Oyingbo Market, Ebute Mẹta.

Apply to the EDITOR.

---

## Eṛia Soro Medicine and General Stores.

SHAPON—ITOKU ROAD, ABEOKUTA.

Ẹ o ri ogun Ikọ, Atura ọkunrin; ogun Ọrin, Igbẹ şoro, Inukikun, ti obinrin ko ba ri nkan osu rẹ; Aitete loyun, Ewo, Apeta, Igbẹ ẹjẹ, Atọsi, Ẹda, ati orişirişi arun ti nba obinrin ati ọkunrin ja, lọ si ibẹ. Owo pọ̃ ni wọn jasi.

---

## ẸNIKEJI,

Aşọ oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3, *St. John Street*, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

## KERE O!

Ọgbẹni M. Winnet Macaulay, ti Ita Oju-oto l'Eko, *(32. Vincent Street)* bẹrẹ iṣẹ Ẹrọ Alọgi; Ẹrọ na si ni agbara Ẹṣin mẹfa. Bi idan ni Ẹrọ yi fi nlọ Igbado; ẹnikeji o sekọ ni o, o ṣagita ni o, re danwo owo rẹ ko tani lara, ẹ tete mu Agbado nyin tọ lọ.

---

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ṢOLANKẸ Oniṣowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, Iṣo loriṣiriṣi, Kọkọrọ (Iṣika) t'ilẹkun ati t'apoti loriṣiriṣi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lᴏriṣiriṣi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọṣan, ati Pakun ti Awo-ẹja loriṣiriṣi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-ṣawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ṣọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

---

## Coffins to suit your Taste.

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. Pereira's, Ṣẹtẹolu Compound, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

## Coffin! Coffin!! Coffin!!!

With excellent workmanship and finish on sale at Paul I. Samuel's Workshop 40, Campbell Street, Lagos.

PAUL I. SAMUEL,
*Builder & Contractor.*

Residence and Office 72, Igboṣere Road Lagos.

---

## The "B'yotiri" Mart.

B. O. JOSEPH,

*Licensed Auctioneer, Commission and Estate Agent. Valuer and Appraiser.*

22, Church Street, Lagos, Nigeria
(Near Carter Bridge).

Undertakes the sale of all kinds of goods also landed properties either by private contract or public auction in any part of Nigeria.

He is also willing to act as commission agent to any of the local firms.

*(Over 21 years' experience in trade.)*

**Cotton, Sundries, Hardware Provisions.**

Prompt rendering of accounts and quick payments. Moderate Charges.

Sales on MONDAYS and THURSDAYS. Commencing at 9 a.m.

*Emergency Excepted*

Patronage is respectfully solicited.

*Telegrams*
"BEN. JOSEPH" Lagos

The Mart and Office,
22, Church Street,
Lagos, Nigeria.

*Residence.*
35, Richards Lane,
Lagos, Nigeria

---

## Books Worth Reading,

On various subjects for Schools and Public Examinations.

Excellent Lectures, Essays, Novels, Dramas, etc. for General Readers and Book-Lovers and comprising Works of prominent English Authors.

R.P.A. Cheap Reprints from Thomas Paine, Ingersoll, MacCabe, Gorham, Herbert Spencer, Stuart Mill, Haekel, Bradlaugh, Huxley, Matthew Arnold, &c. Prices from 1d upwards.

Second-hand Books at about half the published prices; New Books at Bargain prices.

School and Office Stationeries.

Call on, or send enquiry to,
THE ORA BOOK SYNDICATE,
33, Ọbun Eko Street
LAGOS.

# A. Kessler.

*THE INDENT HOUSE*

FOR ALL GOODS FOR THE WEST AFRICAN MARKET.

7, Labinjo Lane,
Williams Street,
***P.O. Box 459***

---

COME AND TRY ME!

FOR THE CONOISSEUR

**Crystall Beer Per Case**

**33s.**

**Genuine Pilsener Urguell**

Per Case

**39s. 6d.**

*BREWED IN PILSEN.*

AND THE

**Padlock Brand Beer**

*48 FULL-SIZED BOTTLES.*

Only

**40s.**

Ẹniti ko ba wa ẹran rẹ a bi obukọ.

---

***A RARE OPPORTUNITY.***

**For Sale by Private Treaty.**

## HOUSE AND LANDED PROPERTY

At No. 1, Glover and Clifford Streets, Ebute Metta.

All that desirable piece or parcel of land, with the buildings thereon consisting of 16 rooms and a shop situate and being at No. 1, Glover and Clifford Streets, Ebute Metta, opening to the streets, and measuring as follows :—

**184 feet 8 inches links by Glover Street**
**184 " 8 " " " Back**
**136 " 3 " " " Denton Street (now Clifford Street)**
**136 " 3 " 4th side.**

MORE OR LESS.

Covered by a Registered Conveyance.

FOR PARTICULARS APPLY TO

**B. O. JOSEPH,**
*Licensed Auctioneer, &c.*

The "B'yotiri" Mart,
22, Church Street, (near Carter Bridge)
RESIDENCE :
35, Richards Lane, Lagos,
*20th October, 1925.*

---

**LAYENI and COLE,**

*General Contractors*

AND

Rents and Debts Collectors and Illiterate documents writers, also undertake the supplying of Fire Woods, Dunnage Woods and Coal.

Monthly payments accepted.

*Please apply to :—*

142, Tokunboh Street or 1, Eugine Street, Agarawu, Lagos.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.